**Ijọ́ Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu**
**Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nàìjíríà**
**ÌSÌN OMI MÁNNÀ**
**Kókó Àdúrà – ÌWÒSÀN PÍPÉ**

**Ijẹwọ: Ìsàíàh 53:5:** Ṣùgbọ́n a ṣa Á lí ọgbẹ́ nítorí ìrékọjá wa, a pa Á lí ara nítorí àìṣedédé wa; ìnà àláfìà wa wà lára Rẹ̀, àti nípa ìnà Rẹ̀ li a fi mú wa lára dá.

## Orin Ìyìn àti Ìjọ́sìn

1. Gbogbo ẹ̀yà àgọ́ ara mi, fọwọ́sowọ́pọ̀ pẹ̀lú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
2. Agbára ìṣọjí, agbára àjínde, agbára ìsọdọ̀tun, bàlé gbogbo ẹ̀yà àgọ́ ara mi, ní orúkọ Jésù.
3. Ẹ̀yà àgọ́ ara mi ìyówù tí ó ti pàdánù iṣẹ́ rẹ̀, bẹ̀rẹ̀ siní ṣiṣẹ́ padà báyìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ẹ̀jẹ̀ Jésù, sọ̀rọ̀ ìyè sínú orí mi, ọkàn mi, ẹ̀dọ̀ mi, kídìrí mi, àpòòtọ̀ mi, ilé-ọmọ mi, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, ní orúkọ Jésù.
5. Mo kọ gbogbo àsọtẹ́lẹ̀ búburú ilé-ìwòsàn, ní orúkọ Jésù.
6. Mo fà lulẹ̀ gbogbo ìbọ̀dè sátánì lórí ẹ̀yà àgọ́ ara mi ìyówù, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo ìkéde ènìyàn lórí ìlera mi tí ó lòdì sí ayé mi, mo fi ẹ̀jẹ̀ Jésù fagilé e, ní orúkọ Jésù.
8. Nípa ọ̀rọ̀ Ọlọ́run tí a fi ipàsẹ̀ rẹ̀ dá ohun gbogbo, Olúwa, jẹ́ kí ayé mi ní ìrírí agbára atòkèwá báyìí, ní orúkọ Jésù.
9. Iná Ẹ̀mí Mímọ́, sọ okun mi dọ̀tun, ní orúkọ Jésù.
10. Ẹ̀jẹ̀ Jésù, sọ okun mi dọ̀tun, ní orúkọ Jésù.
11. Mo tú ara mi sílẹ̀ kúrò nínú ìdè sátánì, ní orúkọ Jésù.
12. Mo fagilé agbára gbogbo ègún lórí ayé mi, ní orúkọ Jésù.
13. Mo ti ilẹ̀kùn ìyówù tí mo ti ṣí í sílẹ̀ lòdì sí ìlera mi, ní orúkọ Jésù.
14. Mo de gbogbo ọkùnrin alágbára lórí ìlera mi, ní orúkọ Jésù.

15. Ilé agbára ọkùnrin alágbára tí wọ́n yàn lòdì sí ìlera mi, yangbẹ, ní orúkọ Jésù.
16. Gbogbo ègún tí wọ́n gún lòdì sí ìlera mi, fọ́, ní orúkọ Jésù.
17. Bàbá mi, sọ mí di àdìtú àrà meèrírí, ní orúkọ Jésù.
18. Níbo ni Olúwa Ọlọ́run Èlíjàh wà? Dìde, kí O sì ṣàtúntò ẹ̀yà ara mi fún àwọn ẹ̀rí tíkòwọ́pọ̀, ní orúkọ Jésù.
19. Gbogbo agbára tó n sọ̀rọ̀ ikú àti àìṣiṣẹ́ dédé sínú ẹ̀yà àgọ́ ara mi ìyówù, kú, ní orúkọ Jésù.
20. Mo gba okun ọ̀tun, iná ọ̀tun, agbára ọ̀tun sínú gbogbo ẹ̀yà àgọ́ ara mi, ní orúkọ Jésù.
21. Bàbá, tú àwọn oníṣẹ́-abẹ ọ̀run jáde láti ṣiṣẹ́ lórí ayé mi, kí O sì jẹ́ kí aṣèti di óṣeéṣe, ní orúkọ Jésù.